Public Disclosure Authorized

Public Disclosure Authorized

RP1795 v2

**Ilé-Iṣẹ́ Ìjọba Àpapọ̀ tó ń rí sí Ọ̀rọ̀ Iṣẹ́-Àgbẹ̀ àti Ìdàgbàsókè Ìgbèríko**
**Àkànṣe-Iṣẹ́ lórí Irè-Oko tó máa ń jẹ́ Lílò Lóòrèkóòrè**

# Ìlànà tó wà nílẹ̀ fún Ìṣíkúròlọsíbòmíràn

## ÌSỌNÍṢÓKÍ ÌMÚṢẸ́ṢE

## Ọ̀rọ̀ Ìpìlẹ̀

Èròǹgbà Agbègbè Ìṣètò Irè-Oko tó máa ń jẹ́ lílò lóòrèkóòrè tó jẹ́ ti Ìjọba Ìpínlẹ̀ Kogí (SCPZ) àti Agbègbè okoòwò ajẹmọ́ṣẹ́-àgbẹ̀ tó jẹ́ ti etílé (ABIR) ni láti ṣèdásílẹ̀ ìdàgbàsókè àjọni nípasẹ̀ ètò àgbẹ̀ alábọ́dé. Iṣẹ̀-àkànṣẹ SCPZ, èyí tí yóò gba owónàá láti ọ̀dọ̀ Báǹkì Àgbáyé, yóò gbìyànjú láti fa ojú àwọn olókoòwò aládàáni mọ́ra nípa: a) ìdàgbàsókè àwọn ohun amáyédẹrùn (iná ìjọba, om ẹ̀rọ, ọ̀nà àti àwọn ohun-èlò àwùjọ mìíràn), b) ìbáṣepọ̀ tó lóòrìn láàrin àwọn àgbẹ̀ àti okoòwò ajẹmọ́ṣẹ́-àgbẹ̀, àti láti ṣèfilọ́lẹ̀ àǹfààní lójúnà ìbáṣepọ̀ tó kuńjú ìwọ̀n, d) pèsè àtìlẹyìn fún ìdàgbàsókẹ̀ àwọn ilé-iṣẹ́ ní SCPZ àti ní agbègbè ABIR. Ní agbègbè tí iṣẹ́ ti rọrùn yí, a ó pe àwọn olókoòwò aládàáni láti wá dá ilé-iṣẹ́ tó ń ṣètò ọ̀gbìn irè-oko tó máa ń jẹ́ lílò lóòrèkóòrè sílẹ̀ ní SCPZ àti láti fi ìmọ̀ kíkún bójútó oko ní ABIR. Èyí tún máa ń fún àwọn àgbẹ̀ abẹ́lé ní àǹfààní láti túbọ̀ yá ẹlòmíràn ní ilẹ̀ oko lò gẹ́gẹ́ bí àgbẹ̀ tó ní àdéhùn lórí ìpèsè ohun ọ̀gbìn.

## Àkànṣe-Iṣẹ́ lórí Irè-Oko tó máa ń jẹ́ Lílò Lóòrèkóòrè

Àkànṣe-iṣẹ́ lórí irè-oko tó máa ń jẹ́ lílò lóòrèkóòrè tí Báǹkì Àgbáyé ń ṣàtìlẹyín owó fún ní òpó mẹ́rin tó gùnlé, àwọn ni:

1. Àtìlẹyìn fún ìdàgbàsókè àwọn ohun-èlò amáyédẹrùn láwùjọ fún SCPZ ní Ìpínlẹ̀ Kogi
2. Àtìlẹyìn fún ìbáṣepọ̀ láàrin àgbẹ̀ àti òwò tó jẹ mọ́ nǹkan àgbẹ̀ pẹ̀lú àǹfààní ètò ọrọ̀-ajé lójúnà àjọṣe òwò àgbẹ̀

3. Ìdàgbàsókè àwọn ilé-iṣẹ́ ní SCPZ àti
4. Ìbójútó àti ìdarí àkànṣe-iṣẹ́.

**Àpèjúwe Àwọn Agbègbè Iṣẹ́ àti Àyíká wọn**

**Agbègbè Kàbà-Bunu:** Kàba-Bunu ni ìjọba ìbílẹ̀ tí ilẹ̀ tí a fẹ́ ṣèfilọ́lẹ̀ iṣẹ́-àkànṣe SCPZ ti Alape sí wà (igba ó lé láàádọ́tasare ilẹ̀, 250ha). Ó wà ní latitude 6.2888831 àti longitude 7.93077. Ó ní ilẹ̀ tó tó 2,757.57km$^2$;àwọn èèyàn tó ń gbé agbègbè náà sì jẹ́ 144, 579. Ọkùnrin jẹ́ 72,639, obìnrin sì jẹ́ 71,940. Ó pààlà pẹ̀lú Ìpínlẹ̀ Kwara àti Lọ́kọ́ja ní apá àríwá, ó pààlà pẹ̀lú Ìjùmú àti Mọ̀pà-Muru ní apá ìwọ̀-oòrùn. Ó pààlà pẹ̀lú Okehi ní apá gúsù àti Lọ́kọ́ja ní apá ìlà-oòrùn. Àwọn ìlú àti ìgbèríko tó wà ní Kaba-Bunu tó wà ní agbègbè ètò ABIR ni Agbadu-Bunu, Ape àti Odo-Ape. Àwọn ìlú mìíràn ní àgbègbè yí ni Tivs, Ebira, Fulani, Tata, Apaa, Aiyede àti Ighun.

**Agbègbè Adavi:** Wọ́n ṣe ìdásílẹ̀ ìjọba ìbílẹ̀ Adavi láti ara ìjọba ìbílẹ̀ Okehi ní ọjọ́ kẹtàdínlọ́gbọ̀n, oṣù kẹjọ, ọdún 1991, nígbà yí náà ni wọ́n dá Ìpínlẹ̀ Kogi sílẹ̀. Ó wà láàrin látítúùdì 7015' sí 8051'N àti lọ́ńgítúùdì 60 sí 60 S.E. Ilẹ̀ ìjọba ìbílẹ̀ náà tó 730,608km$^2$, àwọn èèyàn agbègbè náà jẹ́ 217,219, ọkùnrin jẹ́ 108,891, obìnrin sì jẹ́ 108,328. Lára àwọn ìlú tó wà ní ìjọba ìbílẹ̀ náà ni Ogaminana, Kuroko, Inoziomi, Adavi-eba, Nagazi àti Osarangada. Ọ̀pọ̀ nìnú àwọn ìlú yìí ni ó wà ní ojú-ọ̀nà. Àwọn abúléko tó wà ní agbègbè ABIR ni oko Iresuare ní ìlú Osarangada. Ìdá mẹ́wàá nínú gbogbo àwọn èèyàn tó wà ní Osara-Ngada ni a lè rí ní Iresuare. Ohun kan pàtàkì tí a mọ̀ mọ́ Osara-Ngada ni Dáàmù Osaro èyí tí a ṣẹ̀dá láti ara odò Osaro.

**Agbègbè Lọ́kọ́ja:** Lọ́kọ́ja jẹ́ ìjọba ìbílẹ̀ kan ní Ìpínlẹ̀ Kogí, òun náà sì ni olú-ìlú Ìpínlẹ̀ Kogí. Ó wà láàrin látítúùdì 09.18196 àti lọ́ńgítúùdì 007.17379. Ó pààlà pẹ̀lú Ìpínlẹ̀ Niger ní apá àríwá, Kaba-Bunu ní apa ìwọ̀-oòrùn, Kogí ní apá ìla-oòrùn àti Okehi àti Adavi ní apá gúsù. Àwọn ìpínlẹ̀ tó wà ní agbègbè náà ni Kwara àti Niger, àwọn ìjọba ìbílẹ̀ tó wà ní agbègbè yí ni Ajaokuta,

Adavi, Okehi àti Kaba/Bunu. Agbègbè ìjọba ìbílẹ̀ náà ní ilẹ̀ tó tó 3,180 $km^2$. Tí a bá fi àkọsílẹ̀ ètò ìkànìyàn ọdún 2006 wò ó, àwọn èèyàn ìlú náà jẹ́ 196,643. Ọkùnrin ibẹ̀ jẹ́ 101,145, obìnrin sì jẹ́ 95,498. Ìlú Lọ́kọ́ja ló jẹ́ olú-ìlú ìjọba Gẹ̀ẹ́sì tó wà ní apá àríwá títí di ọdún 1914 tí wọ́n pa Gúsù àti Àríwá pọ̀ dí orílẹ̀-èdè kan. Ó jẹ́ ibùdó okòòwò fún agbègbè ajẹmọ́ṣẹ́-àgbẹ̀ yìí nítorí pé ó wà ní etí Odò Niger àti ti Benue, bẹ́ẹ̀ ni ó súnmọ́ olú-ìlú orílẹ̀-èdè Nàìjíríà, Àbújá. Àwọn ìlú tí iṣẹ́ àgbẹ̀ ti gbilẹ̀, tó wà lábẹ́ ìjọba ìbílẹ̀ Lọ́kọ́ja tí wọ́n sì tún wà ní agbègbè ABIR ni Oshokosho, Iwaa, Jakara, Ọbajana àti Apata.

**Agbègbè Ìjùmú:** Ìlú Ìjùmú wà láàrin látítúùdì 07.84340 àti lọ́ngítúùdì 05.95331. Ilẹ̀ ìlú náà jẹ́1.328.284$km^2$**,** iye àwọn èèyàn tó sì wà ní ìlú náà jẹ́ 118,593: ọkùnrin jẹ́ 59,582 nígbàtí iye obìnrin jẹ́ 59,011. Ìlú náà pààlà pẹ̀lú Mọpa-Muru àti Ìpínlẹ̀ Oǹdó ní apá ìwọ̀-oòrùn, Kaba-Bunu ní apá àríwá àti ìlà-oòrùn àti Pkehi ní apá Gúsù. Lára àwọn ìlú tó wà ní agbègbè yí, tí wọ́n tún wà lábẹ́ ètò ABIR ni Ayégúnlè àti Aiye.

**Agbègbè Okehi:** Ààrin gbùngbùn Ìpínlẹ̀ Kogí ní Okehi wà, ó sì wà láàrin látítúùdì 0.7 sí 07.600147 àti lọ́ńgítúùdì 0.6 sí 0.6.203570. Agbègbè méjì gbòógì ló wà lábẹ́ ìjọba ìbílẹ̀ yí: Ihima àti Eika. Orílẹ̀ mẹ́tàlá ló wà ní ìlú Ihima nígbàti orílẹ̀ mẹ́fà wà ní Eika. Àwọn ìlú tó wà ní Okehi, tó wà ní abẹ́ ètò ABIR ni Ohu, Iru, Irukura, àtiIrukuochakoko. Ìbudó tí àwọn Fúlàní wà jẹ́ ibùdó kan pàtàkì tó wà fún àwọn àtọ̀húnrìnwà. Ilẹ̀ Okehi jẹ́ 672,582$km^2$ nígbà tí àwọn èèyàn inú ẹ̀ jẹ́ 223,574 (ọkùnrin 112,879 àti obìnrin 110,695). Ohun tí a mọ agbègbè yí mọ́ ni aṣọ-híhun, léyìí tí ọ̀pọ̀ àwọn obìnrin wọn máa ń ṣe. Èyí jẹ́ nǹkan bí ìdá márùn-ún nínú ìdá ọgọ́rùn-ún iṣẹ́-oojọ́ ní agbègbè náà.

## Aáwọ̀ àti Ìfigagbága lórí Ilẹ̀

Kò sí ìjà tàbí aàwọ̀ láàrin àwọn ènìyàn tó ń gbé ní àwọn agbègbè yí lórí ọ̀rọ̀ ìlò ilẹ̀ àti ìbágbépọ̀. Àmọ́ ṣá o, ó wà nínú àkọọ́lẹ̀ wí pé ọ̀rọ̀ ilẹ̀ Osara-Ngada

wà nílé ẹjọ́ láàrin Ìjọba Ìbílẹ̀ Okehi àti Adavi. Yàtọ̀ sí èyí, ìjà máa ń wà lóòrèkóòrè láàrin àwọn ìjọba ìbílẹ̀ máráàrún lórí bí àwọn Fúlàní ṣe má ń kó àwọn màálù wọn jẹ̀. Àwọn àgbẹ̀ agbègbè máa ń fi ẹ̀hónú hàn pé àwọn màálù Fúlàní a máa ba oko àwọn jẹ́, èyí tí ó máa ń fa ìjà ńlá nígbà mìíràn.

Gẹ́gẹ́ bí àkànṣe-iṣẹ́ lórí ìlànà ìyanjú-aáwọ̀, àti ẹ̀kọ́ tí ó wà nínú ìgbésẹ̀ Báńkì Àgbáyé ní àkànṣe-iṣẹ́ FADAMA, ìkíní àti ìkẹta, a ó ṣèfilọ́lẹ̀ kọmití láti rí sí aáwọ̀ tó wà láàrin àwọn àgbẹ̀ àti àwọn tó ń kó ẹran jẹ̀. A ó dá awọn kọmití sílẹ̀ ní àwọn abúlé, Ìjọba Ìbílẹ̀ àti ní ìpele Ìpínlẹ̀, láti yánjú àwọn àríyànjiyàn tó le fojúhàn níbí ìlò àwọn ohun-èlò agbègbè yìí. Àwọn tí yóò wà nínú kọmití báyìí ni àwọn tó wà láti ọ̀dọ̀ àwọn ẹgbẹ́ àti àjọ. Ojúṣe wọn ni láti rí i dájú pé ìbáṣepọ̀ àti ìbágbépọ̀ tó dán mọ́rọ́n wà láàrin àwọn agbẹ̀ olóhun ọ̀gbìn àti àwọn adaran, láti rí i pé àlàáfíà jọba ní agbègbè náà, láti yanjú àwọn aáwọ̀ tó ti wà nílẹ̀, kí wọ́n máa ṣèpàdé lóòrèkóòrè láti le mú èròngbà àti àfojúsùn kọmití náà wà sí ìmúṣẹ.

**Ibi tíṣẹ́ yóò dé àti àwọn ọ̀nà ìgbàṣiṣẹ́ RPF**

Ìlànà fún ìṣíkúròlọsíbòmíràn (RPF) ti jẹ́ lílàsílẹ̀ ní ọ̀nà àjọṣepọ̀ pẹ̀lú àkànṣe-iṣẹ́ SCPZtí a ti ṣàlàyé síwájú. RPF yìí yóò wà fún ilẹ̀-gbígbà, ìṣíkúrònínìbìkan, ìsanwógbà-má-bìínú, dídá ọ̀nà oúnjẹ òòjọ́ àti àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ mìíràn ní Ìpínlẹ̀ Kogí sílẹ̀, ó ní í ṣe pẹ̀lú àwọn wọ̀nyí:

1. Òwò tí àkànṣe-iṣẹ́ SCPZ ṣe àtìlẹyìn owó fún, pẹ̀lú àfikún àwọn ohun-èlò amáyédẹrùn àti àwọn okòòwò mìíràn tí ìṣúná rẹ̀ yóò wà lábẹ́ òpó kìíní àti ìkejì.
2. Ìfilọ́lẹ̀ ọ̀gangan agbègbè SCPZ, tó jẹ́ nǹkan bíi igba ó lé láàáádọ́tasare ilẹ̀, pẹ̀lú àwọn okòòwò aládàáni ti àwọn ayálẹ̀lò lábẹ́ ọ̀gangan agbègbè SCPZ.

3. Okòòwò ti àwọn ayálẹ̀lò, tó wà lábẹ́ oko tí a fi lọ́lẹ̀ nínú oko ńlá mìíràn, ní ABIR, ilẹ̀ tó wà fún iṣẹ́ yìí jẹ́ nǹkan bíi ẹgbàá mẹ́ẹ̀ẹ̀dógún sare ilẹ̀ (tí a ò tí ì wọn ilẹ̀ ọ̀hún tán).

Fún èrèdí RPF nígbà náà, ọ̀rọ̀ tí a pè ní "àkànṣe-iṣẹ́" yóò túmọ̀ sí àwọn kókó mẹ́ta tí a tò sókè yìí, "àkànṣe-iṣẹ́ kéékèèké" pẹ̀lú PPA yóò sì ní ìtumọ̀ bí a bá ṣe lò wọ́n.

Láfikún, Ìjọba Ìpínlẹ̀ Kogi, ti fi ìfẹ́ hàn láti ṣàmúlò ètò RPF sí àwọn okòòwò tó jẹ́ mọ́ SCPZ tó tún wà lábẹ́ ABIR, wọ́n ṣèyí láti rí i pé bí wọ́n ṣe ń ṣètò ọ̀hún kò yàtọ̀ rárá fún gbogbo ìgbà tí wọn yóò fi ṣe ètò ABIR.

Ní àkókò ìpalẹ̀mọ́ àkànṣe-iṣẹ́, àwọn àlàyé bíi ìbudó àwọn àkànṣe-iṣẹ́ kéékèèké, ọ̀nà tó yẹ láti gbé páìpù gbà, ìdánimọ̀ àwọn olùdókòwò àti ìbùdó ilé-iṣẹ́ kò tíì jẹ́ mímọ̀. Nítorí náà, a ṣètò àkọ́ọ́lẹ̀ RPF yí láti le pèsè ìlànà tó yẹ láti tẹ̀lé fún ìpalẹ̀mọ́ àwọn RAP ẹnìkọ̀ọ̀kan nígbà tí ibùdó àkànṣe-iṣẹ́ ní pàtó, ìṣe àti ìlapa-iṣẹ́ yóò ti jẹ́ mímọ̀.

**Ìlànà Iṣẹ́ tó ní í ṣe pẹ̀lú Òfin**

Ètò RPF yìí gúnlè òfin ìlò ilẹ̀ ti orílẹ̀-èdè Nàìjíríà tọ̀dún-un 1978 àti ti BÁńkì Àgbáyé OP 4.12. Àwọn ibi tó ṣe pàtàkì nínú àwọn òfin méjéèjì yí àti àwọn ìtúpalẹ̀ àlàfo ni a ṣàlàyé sísàlẹ̀ yí. Tí ìyàtọ̀ bá wà láàrin ofin orílẹ̀-èdè àti òfin OP 4.12, òfin tó ga jùlọ ní yóò borí:

| Abala | Òfin Nàìjíríà | Báńkì Àgbáyé OP 4. 12 | Àwọn Ìlànà àti dí àwọn Ààfo |
|---|---|---|---|
| Ìdínkù ìṣílọsíbòmíràn | Kò sí ìdí láti gba àwọn àǹfààní ìlapa àkànṣe-iṣẹ́ láti le dín ìdí fún | Kò gbọdọ̀ sí àyè fún fífi tipá ṣí kúrò tí àǹfààní bá wà fún èyí, kí á wo àwọn | Ìṣètó ọ̀nà ìgbàṣiṣẹ́ tó rọ̀ mọ́ ìṣe yóò jẹ́ gbígbéyẹ̀wò láti dín ọ̀rọ̀ ìṣílọsíbòmíràn kù. |

| | | | |
|---|---|---|---|
| | ìṣíkúrò tàbí ìlékúrò kù. | ọ̀nà mìíràn tí a lè gbé ìlapa àkànṣe-iṣẹ́ gbà. | |
| Ìròyìn àti Ìfọ̀rọ̀lọ̀ | Ó bá òfin mu fún gómìnà láti gba ilẹ̀ tó ba tí fí ìkìlọ̀ sílẹ̀. Kò sí ìlò fún ìfọ̀rọ̀lọ̀. | Ó jẹ́ dandan láti fí ọ̀rọ̀ lọ àwọn PAP, kí wọ́n sì kópa nínú ètò ìṣílọsíbòmíràn | A gbọdọ̀ fí ọ̀rọ̀ lọ PAP, kí wọ́n sì kópa nínú ètò ìṣílọsíbòmíràn |
| Àkókò ìsan owó gbà-má-bìínú | Òfin kò sọ nǹkankan nípa àkókò láti san owo o gbà-má-bìínú | Kí owó gbà-má-bìínú jẹ́ sísan kí wọ́n tó bẹ̀rẹ̀ iṣẹ́ lórí ilẹ̀ náà àti kí wọ́n tó ṣí kúrò. | Kí owó gbà-má-bìínújẹ́ sísan kí wọ́n tó bẹ̀rẹ̀ iṣẹ́ lórí ilẹ̀ náà àti kì wọ́n tó ṣí kúrò. |
| Dídá iṣẹ́ òòjọ́ padà. | Kò sí ìpèsè òfin kankan lóri dídá iṣẹ́ òòjọ́ padà | Ó fi lélẹ̀ pé àwọn tí a gbà ilẹ̀ wọ́n/àwọn PAP gbọ̀dọ́ rí ìrànwọ́ gbà nípa ìgbé-ayé ìrọ̀rùn, tàbí, ó kéré jù, kí wọ́n máa gbé irú ìgbé-ayé tí wọ́n ń gbé kí a tó gba ilẹ̀ wọn. | Ètò àti pèsè iṣẹ́ òòjọ́ yóò wà nílẹ̀ fún àwọn PAP. |
| Ìlànà Ìfẹ̀hónú-hàn. | Kọmití tó wà lóri ìlò ilẹ̀ àti ilẹ̀ pípín tí gómìnà fi lélẹ̀ ní yóò ní ojúṣe àti rí sí | Ó fi lélẹ̀ pé kí ètò ìrísí ọ̀rọ̀ ìfẹ̀hónú-hàn lórí ìlò ilẹ̀ kó tètè jẹ́ gbígbé dìde, èyí tí yóò ní àwọn | Ètò ìrísí ọ̀rọ̀ ìfẹ̀hónú-hàn lórí ìlò ilẹ̀ (GRC)yóó tètè jẹ́ gbígbé dìde, fífi ọ̀nà ìbílẹ̀ yanjú ọ̀rọ̀ yóò jẹ́ |

| | | | |
|---|---|---|---|
| | gbogbo aáwọ̀/ìfẹ̀hónú-hàn àti ètò gbà-má-bìínú | PAP gẹ́gẹ́ bí ọ̀kan lára wọn, èyí tí yóò nífẹ̀ẹ́ sí ìyanjú ọ̀rọ̀ lọ́nà ìbílẹ̀. Ilé-ẹjọ́ ni yóò jẹ́ ibi tí àwọn PAP yóò gbà lọ tí àbájáde ètò yí kò bá tẹ̀ wọn lọ́rùn. | àtẹ́wọ́gbà fún àwọn aáwọ̀ tó wà lórí àkànṣẹ-iṣẹ́. Àwọn PAP tàbí àwọn aṣojú wọn yóò wà nínú ìgbìmọ̀ (GRC) yìí. |
| Àwọn tó ní igi-owó àti igi èso | Owó tó tó iye àwọn nǹkan wọ̀nyí tí a gbà, gẹ́gẹ́ bí òṣìṣẹ́ ìjọba tó wà nípò àti ṣe èyí ni yóò jẹ́ sísan | Owó tí àwọn igi náà tó lọ́jà, àti owó tí wọ́n fi gbìn wọ́n, tí wọ́n fi tọ́jú wọ́n dàgbà àti owó òṣìṣẹ́. | Owó tí àwọn igi náà tó lọ́jà, àti owó tí wọ́n fi gbìn wọ́n, tí wọ́n fi tọ́jú wọ́n dàgbà àti owó oṣìṣẹ́. |
| Ilẹ̀ ìlú tó ní ìwé lórí | Owó sísan fún ìlú bẹ́ẹ̀, olóyè tàbí olóri ìlú náà fún àǹfààní gbogbo ìlú | Fífi ilẹ̀ rọ́pò ilẹ̀ tàbí ọ̀nà láti tu àwọn ìlú nínú tí wọ́n fara mọ́. | Fífi ilẹ̀ rọ́pò ilẹ̀ tàbí ọ̀nà láti tu àwọn ìlú nínú tí wọ́n fara mọ́. |
| Ilẹ̀ oko | Wọ́n ní àṣẹ sí ilẹ̀ oko mìíràn | Wọ́n ní àṣẹ sí ilẹ̀ oko mìíràn | Wọ́n ní àṣẹ sí ilẹ̀ oko mìíràn |
| Ilẹ̀ lásán | Kò sí ètò gbà-má-binú kankan | Ètò ilẹ̀ fún ilẹ̀ | Ètò ilẹ̀ fún ilẹ̀ |
| Ipò òfin tó wà nílẹ̀ lórí àwọn onílẹ̀ | Owó gbà-má-bìínú tí yóò tó owó tí ẹni tó yá ilẹ̀ lò san ní | Ìdábàá ilẹ̀ fún ilẹ̀ tàbí ọ̀nà mìíràn láti tu ẹni náà nínú ní kíkún | Ìdábàá ilẹ̀ fún ilẹ̀ tàbí ọ̀nà mìíràn láti tu ẹni náà nínú ní kíkún |

| | | | |
|---|---|---|---|
| Ajílégbé | Kò yẹ ní ilẹ̀ gbígbà àmọ́ wọ́n lè gba owó gbà-má-bìínú lórí ohun-ọ̀gbìn | Wọn ó fún wọn ní àǹfààní ilégbèé pẹ̀lú owógbà-má-bìínú lórí àwọn nǹkan ìní wọn tó bàjẹ́; àti àwọn ọ̀nà láti mú ìgbé-ayé dẹrùn tí wọ́n nílò | Wọn ó fún wọn ní àǹfààní ilégbèé pẹ̀lú owógbà-mábìínú lórí àwọn nǹkan ìní wọn tó bàjẹ́; àti àwọn ọ̀nà láti mú ìgbé-ayé dẹrùn tí wọ́n nílò |
| Àwọn onílé tí kò lálòpẹ́ | owógbà-má-bìínú lórí iye tí ilé náà tó (àyé wá fún ìdínníyelórí) | Ní ẹ̀tọ́ láti gba owó tó kájú ìṣíkúrò àti owó àwọn òṣìṣẹ́ kí wọ́n tó kó ẹrù rẹ̀ | Ní ẹ̀tọ́ láti gba owó tó kájú ìṣíkúrò àti owó àwọn òṣìṣẹ́ kí wọ́n tó kó ẹrù rẹ̀ |
| Àwọn onílé tí ó lálòpẹ́ | Ṣíṣí lọ sí ibòmíràn tí ó dára tàbí fífún wọn ní owógbà-má-bìínú lórí iye tí ilé náà tó | Ní ẹ̀tọ́ láti gba owó tó kájú ìṣíkúrò àti owó àwọn òṣìṣẹ́ kí wọ́n tó kó ẹrù rẹ̀ | Ní ẹ̀tọ́ láti gba owó tó kájú ìṣíkúrò àti owó àwọn òṣìṣẹ́ kí wọ́n tó kó ẹrù rẹ̀ |
| | ọdún tí a gba ìwé ilẹ̀. | | |
| Àwọn ayálẹ̀lò | Wọ́n lẹ́tọ̀ọ́ sí owó gbà-má-bìínú tí yóò jẹ́ iye ẹ̀tọ́ tí wọ́n ní lórí ilẹ̀ náà | Wọ́n lẹ́tọ̀ó sí ìtunìnínú nípaàwọn ohun ọ̀gbìn tí ó wà lórí ilẹ̀ tí wọ́n yá lò àti àwọn ẹ̀tọ́ mìíràn, àti pẹ̀lú dídá iṣẹ́ òọ̀jọ́ wọn padà. | Ìtunìnínú nípa ohun ọ̀gbìn tí ó wà lórí ilẹ̀ tí wọ́n yá lò àti àwọn ẹ̀tọ́ mìíràn, àti pẹ̀lú dídá iṣẹ́ òọ̀jọ́ wọn padà. |

**OríṣiríṣiÀwọn Ipa Òdì Àwùjọ àti Ìsọ̀rí Àwọn Tí Ó Kàn**

Èrò wa ni pé ètò SCPZ lórí ilẹ̀ gbígbà àti àwọn ètò mìíràn bẹ́ẹ̀ yóò fa oríṣiríṣi ipa fún ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn ẹgbẹ́ àti àwọn èèyàn bí ó ti wà nísàlẹ̀ yìí:

| No | Irú Ipa | Àpejúwe Ipa Tó Lè Yọjú | Àwọn Ẹgbẹ́ tó kàn |
|---|---|---|---|
| 1 | Pípàdánù ilẹ̀ ìgbòrò àti ilẹ̀ oko | Ilẹ̀ gbígbà fún iṣẹ́ yìí yóò kan àwọn ilẹ̀ oko, ilẹ̀ ìgbòrò àti ilẹ̀ tí àwọn èèyàn ń lò fún oríṣi nǹkan nìnú ìgbé-ayé wọn | Àwọn onílẹ̀, ayálégbé, àgbẹ̀, darandaran, ọdẹ |
| 2 | Pípa ilò ilẹ̀ dà àti ilẹ̀ tó wọ́n | Ohun tí a ń lo ilẹ̀ fún le fa kí ilẹ̀ wọ́n léyìí tí ó sì lè fa ìjà lórí ilẹ̀ náà | Ẹgbẹ́ àwọn àgbẹ̀, àwọn ará agbègbè àti àwọn tó ń lo ilẹ̀ |
| 3 | Ìṣíkúrò | Ó ṣeéṣe kí a rí ìṣíkúró aláìyọ́núsí. Èyí lè mú wọn jìnna sí àwọn ẹbí, ará, ọ̀rẹ́ àti àṣà wọn | Àwọn ènìyàn agbègbè àti àwọn tó ń gbé ibẹ̀ |
| 4 | Pípàdánù ilẹ̀ fún ìjẹ ẹran | Igbó ṣíṣán àti lílò nò níí jẹ́ kí àwọn darandaran ríbi bọ́ ẹran tàbí bọ́ ara wọn | Àwọn Fulani tó ń gbé ibẹ̀ àti àwọn darandaran aṣíkìrí |
| 5 | Ìpàdánù ohun ìní adánidá | Ilẹ̀ gbígbà àti ìsàgàtì ilẹ̀ yóò jẹ́ kí àwọn èèyàn pádánù àwọn ohun àlùmọ́nì bíi àwọn nǹkan inu omi, ti inú igbó, àwọn ẹja, ẹran ìgbẹ́ | Ọ̀wọ́ àwọn tí kò lágbara, àwọn obìnrin |
| 6 | Pípàdánù ilé | Okòwò SCPZ lè já sí ìṣíkúrò aláìyọ́núsí àwọn ènìyàn tó le mú wọn pàdánù ilé àti ọ̀nà wọn | Àwọn onílé, ayálégbé, oníṣòwò |

| | | | |
|---|---|---|---|
| 7 | Ìpàdánù iṣẹ́ | Èyí lè jẹ́ àwọn tó ń ṣiṣẹ́ tẹ́lẹ̀tẹ́lẹ̀ lórí ilẹ̀ tí a gbà ati àwọn tó ní ṣọ́ọ̀bù síbẹ̀ | Àwọn obìnrin, ọ̀dọ́, apẹja, darandaran |
| 8 | Pípàdánù àwọn ohun àjogúnbá ajẹmáṣà | Èyí lè jẹ́ bíi nǹkan ìní àjogúnbá, ojúbọ, oórì | Àwọn ènìyàn agbègbè |
| 9 | Ìjà abẹ́lé | Ọ̀rọ̀ ìfúnni lówó gbà-má-bìínú lè dájà sílẹ̀ láàárín ẹbí àti alájọgbé. Ìṣíkúrò lọ sí ibòmíràn lè mú ìjà wá láàárín àwọn àlejò àti àwọn tó ni ilẹ̀ | Àwọn agbègbè tí ó kàn, òṣìṣẹ́ olùṣíkúrò àti àwọn olùdókòwò |
| | Aáwọ̀, ìgbẹ́jọ́ ilé-ẹjọ́ àti yánpanyánrin | Aáwọ̀, ìgbẹ́jọ́ ilé-ẹjọ́ àti yánpanyánrin lè má kan agbègbè náà nìkan, ó tún lè dí ìmúṣe iṣẹ́ náà lọ́wọ́ | Àwọn olùdókòwò, ìjọba, àti àwọn ènìyàn agbègbè |

Àfojúbù Iye Àwọn Tí Ipa Iṣẹ́ Yìí Kàn

A kò lè fojú bu iye àwọn tí ipa iṣẹ́ yìí lè kàn ní àkókò yìí; ìdí ni pé (a) a ò tíì mọ ibi tí iṣẹ́ SCPZ yóò pin sí; (b) ìjíròrò ṣì ń lọ lọ́wọ́ láàárín Cargill àti Ìpínlẹ̀ Kogí lórí ibi tí ilẹ̀ oko Cargill fẹ̀ dé; (c) Awọn ohun àmúṣagbára fún iṣẹ́ náà ò tíì sí nílẹ̀; (d) A kò tíì mọ bí ọjọ́ ọ̀la okòwò ìṣòwò ohun-ọ̀gbìn lábẹ́ ABIR yóò ti rí. Yàtọ̀ sí èyí, lábẹ́ àlàkalẹ̀ kan tó jẹ́ ti àlà ilẹ̀ oko Cargill, àfojúbù iye àwọn ènìyàn PAP tó ẹ̀gbàá mẹ́rin 8000 tí wọn yóò nílò láti ṣí kúrò, àti àwọn ẹ̀gbàá 2000 mìíràn tí wọ́n ń gbé ní òdìkejì ilẹ̀ náà àmọ́ tí wọn yóó pàdánù ilẹ̀ tí wọ́n ń lò fún iṣẹ́ àgbẹ̀, gbígbín igi owó àti ìdaran jẹ̀. Àlàkalẹ̀ mìíràn lè dín iye

àwọn èèyàn yìí kù sí ẹgbàá 2000, àti pé èrò nípa àwọn ọ̀nà mìíràn tí a lè gbà dípò ká mú àwọn èèyàn ṣí kúrò ń lọ lọ́wọ́.

**Àwọn àlàkalẹ̀ láti mú ipa òdì kúrò tàbí dín kù**

Àwọn ìlànà OP 4.12 nílò pé bí a bá ti lè gbìyànjú ẹ̀ tó, ká yàgò fún ìṣíkúrò aláìyọ́núsí pátápátá tàbí kí a dín in kù. Ní ìbámu pẹ̀lú èyí, àwọn alákòóso iṣẹ́ náà yóò yẹra/dín ipa òdì iṣẹ́ náà kù nípa àwọn ìlànà ìsàlẹ̀ yìí:

- Pípa àwòrán-èrò dà àti pípe àwọn tí ọ̀rọ̀ kàn sọ́rọ̀;
- Lílo àwọn ọ̀nà tó ti wà nílẹ̀ tẹ́lẹ̀ tí a bá ń pilẹ̀ àti ṣe àwọn nǹkan bíi títún ọ̀nà ṣẹ, ọ̀nà páìpù onígáàsì, iná mọ̀nàmọ́ná;
- Gbígba àwọn ènìyàn agbègbè tí ọ̀rọ̀ kàn sí iṣẹ́ APIR náà;
- A ó dín ipa òdì kù tàbí kía mú un kúrò pátápátá tí a bá lè pèsè àyè oko ìjẹ fún àwọn ẹran ọ̀sìn láàárín ABIR.

**Àwọn ìgbésẹ̀ Ìméwudínkù**

Ipa òdì tí a kò bá lè yàgò fún ni yóò bí fífunni ní owó gbà-má-bìínú, èyí ni a ó mọ̀ nínú yíyẹ àwùjọ wò ní ipele ìpalẹ̀mọ́ fún RAP ní agbègbè ilẹ̀ tí a gbà. A ó wá lo àlàkalẹ̀ ìfúnni ní owó gbà-má-bìínú nígbà tí a ó lo àwọn ètò (1) tí ó lófin nínú, (2) bí a ti ń yan àwọn tí irú owó yìí tọ́ sí, (3) wíwọn bí nǹkan ti níyelórí tó (4) ìlànà mímú iṣẹ́ náà ṣe (5) àwọn ọ̀nà tí owó ń gbà jáde, àti (6) ìbójútó àti àgbéyẹ̀wò. Ìgbésẹ̀ mímú igbé-ayé àwọn èèyàn padà sí rere yóò ní àwọn àlàyé lórí àwọn ọ̀rọ̀ bíi (1) iye owó tó ń wọlé fún àwọn tí ọ̀rọ̀ kàn, (2) àwọn ọ̀nà ìgbé-ayé aláìjẹmówó mìíràn, (3) àwọn òté àti ìfà fún bí owó ti ń wọlé, (4) iye àwọn tí kò lè padà sí iṣẹ́ tí wọ́n ń ṣe tẹ́lẹ̀, àti (5) ọgbọ́n ìmú-nǹkan-ṣe tí àwọn tí ọ̀rọ̀ kàn ní tẹ́lẹ̀.

A ó ya àwọn tí kò lágbára tí ipa òdì iṣẹ́ yìí kàn sọ́tọ̀, a ó sì fún wọn ní owó gbà-má-bìínú nígbà tí àsìkò rẹ̀ bá tó. Àwọn ohun tí a fi pín àwọn yìí ní àwọn tí ọjọ́ orí wọn lé ní márùndínláàádọ́rin, àwọn aláàbọ̀ ara/alárùn ọpọlọ,

àwọn obìnrin, àwọn àgbẹ̀ àti darandaran tó ń ṣí kiri, àwọn opó, àwọn ọmọ aláìlóbìí àti àwọn aláìsàn.

## Ìlẹ́tọ̀ọ́ Lábẹ́ Òfin Láti Gbowó

RPF yìí níran pé gbogbo irú ipa òdì tí ilẹ̀ gbígbà alábọ́dé tàbí ti ọlọ́jọ́ pípẹ́ lè fà lábẹ́ iṣẹ́ yìí ni kí a mú ìdínkù bá láì sọsẹ̀. Fún ìdí èyí, ìsọ̀rí ìlẹ́tọ̀ó yìí ni a kọ sísàlẹ̀ yìí:

a) Awọn tó ní ìtìlẹ́yìn òfin láti dá ilẹ̀ ní (bí àwọn onílẹ̀ afòfingbé, ajẹmáṣà, ajẹmọ́ṣe àtẹ̀sìn gẹ́gẹ́ bí ó ti wà lábẹ́ òfin orílẹ̀-èdè/ìpínlẹ̀ ní ilẹ̀ Nàìjíríà)

b) Awọn tí kò ní ìtìlẹ́yìn òfin láti dá ilẹ̀ ní ní àkókò ìkànìyàn àmọ́ tí wọ́n lè fọwọ́ sọ̀yà pé àwọn ló ni ilẹ̀ yìí lọ́nà tí ó bófin ìpínlẹ̀/orílẹ̀-èdè Nàìjíríà mu tàbí nípa ìlànà tí a mọ̀ sí RPF.

c) Awọn tí kò ní ìtìlẹ́yìn òfin lórí ilẹ̀ tí wọ́n ń lò àmọ́ wọ́n ń gbé ibẹ̀ kí déètì tí a kéde láti lo ilẹ̀ náà tó dé.

Àwọn tó wà ní ìpele (a) àti (b) ni a ó fún ní owó gbà-má-bìínú àti àwọn ìrànlọ́wọ́ mìíràn gẹ́gẹ́ bí òfin náà ti sọ. Àwọn (c) ni a ó pèsè ìrànlọ́wọ́ ṣísí lọ sí ibòmíràn fún dípòkí a ó fi fún wọn ní owó gbà-má-bìínù fún ilẹ̀ tí wọ́n ń lò, pẹ̀lú àwọn ìrànlọ́wọ́ mìíràn gẹ́gẹ́ bí ó ti wà nínú ìlànà yìí. Àwọn ènìyàn tó wà ní ipele mẹ́tẹ̀ẹ̀ta ni wọ́n ní ẹ̀tọ́ sí owó gbà-má-bìínú fún àwọn nǹkan ìní wọn tí kò jẹ mọ́ ilẹ̀. Yàtọ̀ fún èyí, àwọn tí ó bá bẹ̀rẹ̀ sí í lo ilẹ̀ yìí lẹ́yìn tí a bá ti poloñgo déètì ìṣíkúrò kò ní owó kankan láti gbà.

## Àwọn Ọ̀nà Ìparí Aáwọ̀

Èróńgbà ìlànà ìparí aáwọ̀ ni láti:

i. Pèsè ọ̀nà ìfẹjọ́sùn àti ìyanjú ìjàkíjà tó le wáyé ní àkókò ìmúṣẹ́ṣe àti ìgbèrò fún sísan owó gbà-má-bìínú tàbí nígbà tí iṣẹ́ bá ti bẹ̀rẹ̀ tán fún àwọn tí ọ̀rọ̀ kàn.
ii. Ríi dájú pé a mọ̀ àwọn ìgbésẹ̀ ìparí aáwọ̀ tí kò ní ìkùnsínú àti pé a sì gbé wọn lọ́nà tí ó tẹ́ àwọn èèyàn lọ́rùn.

- Yàgò fún lílọ sí ilé ẹjọ́.

Àwọn ọ̀nà gbòógì tí a fi ń yanjú aáwọ̀ ni:

- Gbígba ìfẹjọ́sùn sílẹ̀;
- Gbígbèrò lórí ìgbésẹ̀ ìparí aáwọ̀;
- Ṣíṣàyẹ̀wò ìgbésẹ̀ ìparí aáwọ̀;
- Fífi sùúrù parí aáwọ̀; àti
- Ìfàyẹ̀gba kòtẹ́milọ́rùn àti àwọn ìgbésẹ̀ mìíràn;

## Ẹ̀tọ́ àwọn iléeṣẹ́

Àwọn iléeṣẹ́ tí ọ̀rọ̀ ìmúṣẹ́ ìparí aáwọ̀ ṣe ni:

- Alákòóso Àgbà láàárín PMU
- Alága Agbègbè Ìjọba Ìbílẹ̀ náà
- Aṣojú Ẹ̀ka-Ilẹ̀ ti Ìpínlẹ̀ Kogi ní Agbègbè Ìjọba Ìbílẹ̀ náà
- Alákòóso Ilẹ̀ Gbígbà àti Ìṣílọsíbòmìíràn ti LMU
- Oníṣẹ́ Àkànṣe Àwùjọ ti LMU/PMU
- Amojú-ẹ̀rọ ti PMU
- Onímọ̀ Ààfọ̀rọ̀lọ̀

## Ìmójútó Ìdásí àti Ètò Ìṣàgbéyẹ̀wò

Láti ŕii dájú pé a ṣe iṣẹ ìṣílọsíbòmìíràn ní ìbámu pẹ̀lú àwọn òfin tó rọ̀ mọ́ ọn, àwọn ẹgbẹ́ ìmójútó àti ìṣàgbéyẹ̀wò (MET) tí a ó dá sábẹ́ Ìjọba Ìpínlẹ̀ Kogi yóò mójúto; wọn ó sì gbe ọ̀rọ̀ yẹ̀ wò lábẹ́lé. Àwọn ẹgbẹ́ ìmójútó àti

ìṣàgbéyẹ̀wò (MET) yìí yóò ṣàgbékalẹ̀ ètò ìmójútó àti ìṣàgbéyẹ̀wò (MEP). Ìpìlẹ̀ MEP yìí ni pé: (i) wọn ò níí jẹ́ kí ìgbé-ayé àwọn ènìyàn, ìdílé àti àwùjọ pẹ́lú ipa iṣẹ́ tó kàn wọn relẹ̀, dípò bẹ́ẹ̀, wọn ó mu wọn dára síi ni; (ii) wọn yóò mu àwọn àwùjọ tí ipa iṣẹ́ yìí kàn dára síi; (iii) wọn yóò máa paná ìjà tàbí aáwọ̀. Àwọn alábòójútó yìí yóò máa jábọ̀ déédé (yóò dára bó bá lè jẹ́ lóṣooṣù) fún Alákòóso ní PMU, òun sì gbọ̀dọ̀ fi ṣọwọ́ sí FMARD. Ohun tí yóò wà nínú ìjábọ̀ yìí ni ìpínwó gbà-má-bìínú, oríṣìríṣi àwọn ìfẹjọ́sùn, àwọn ìgbésẹ̀ ìparí aáwọ̀, àti àti àwọn ọ̀nà ìtúbọ̀rísí.

## Aáyan ògbúfọ̀ sí àwọn olórí ẹ̀ka-èdè tó wà ní agbègbè iṣẹ́

Kí àwọn ará àwùjọ tó wà ní agbègbè iṣẹ́ yìí, ní pàtàkì, àwọn tí ọ̀rọ̀ lè kàn (PAP), lè ní òye nípa ohun tó ń ṣẹlẹ̀, a ṣe aáyan ògbufọ̀ ìjábọ̀ ìsọníṣókí ìmúṣẹ́ṣe náà sí olórí ẹ̀ka-èdè agbègbè SCPZ àti ABIR (Yorùbá).

## Ìṣíṣọlójú-ọ̀rọ̀

A ṣe àgbékalẹ̀ RPF náà pẹ̀lú ìfọ̀rọ̀lọ̀ PMU ti ìpele Ìjọba Àpapọ̀, àwọn MDA ti ìpínlẹ̀, àwọn CBO/NGO àti àwọn ẹgbẹ́ àwùjọ mìíràn. A ó ṣíṣọ lójú RPF náà ní gbàgede gẹ́gẹ́ bí ìwé adádúró tó wà fún àyẹ̀wò àti ìdásọ́rọ̀ Ìjọba Àpapọ̀/Ìpínlẹ̀, Iléeṣẹ́ Ìjọba Arísí Ọ̀rọ̀ Àyíká. Èyí ni yóò wáyé ní àwọn agbègbè tí a yàn pẹ̀lú Ìjọba Àpapọ̀, Ìpínlẹ̀ Kogi àti àwọn Ìjọba Ìbílẹ̀, pẹ̀lú àwọn ilé ìfọ̀rọ̀tónilétí ti Báńkì Àgbáyé. Àwọn RAP ti oníkálukú ni a ó ṣe létò fún iṣẹ́ àkànṣẹ alábọ́dé kọ̀ọ̀kan ní ìbámu pẹ̀lú ìlànà tí ó wà nínú RPF yìí, a ó sì máa ṣíṣọ lójú wọn bákan náà.